# IROHIN IMỌLE

*IMỌLE ORE AIYE, TENI GBOGBO LAWA*

NO 877 MONDAY DECEMBER 21, 1964 [2D]


## Babalọla Bere fun Abo Ọlọpa

IBADAN:- Oloye Richad Babalọla, ọkan ninu awọn ọmọ Ile Igbimọ Agba oṣelu ati ọmọ ẹgbẹ Dẹmọ ti o jẹri ni Kotu nigba ẹjọ Oloye Ọbáfẹmi Awolọwọ, ti tẹ waya ranṣe si Oloye ọdọfin Bello, ọga agba fun awọn Ọlọpa Ipinlẹ Iwọ Orun. wipe, kinwọn fun on ni Ọlọpa lati ma wa pẹlu on ni gbogbo igba nitoripe awọn kannwa ọna lati doju on bolẹ.

Ninu waya na, ọgbẹni Babalọla ṣe alaye pe, "gbogbo awọn ohun ti mo ni ati ẹmi mi lo wa ninu ewu ni a s i k e yi, awọn ọmọ ẹgbẹ Ọlọpẹ fẹ pa mi." Waya yi ni Oloye Babalọla tẹ lati ilu rẹ ni Ẹffọn Alaye.

Oloye Babalọla tun ṣe afikun ninu waya na wipe, lẹnu lọlọ yi ni mọto ayọkẹlẹ ti on ra ni ẹdẹgbẹsan pọnun £1.700) ati ile on ni awọn enia na ti bajẹ patapata, awọn ti Oloye na pe ni "ẹhanna" Siwaju si I, Oloye na ni on ti bẹrẹ si gbọ hunnu hunu ni abẹlẹ wipe, awọn ọmọ ẹgbẹ Ọlọpẹ nwa ọna lati pa mi, nitoripe mo jẹri lodi si Awolọwọ ni asiko ẹjọ rẹ ninu ile ẹjọ"

Ni ipari, Oloye Richard Babalọla kesi ọga Agba awọn Ọlọpa lati tete mojuto ọrọ na, ki nwon o si fun on ni awon Ọlopa lati ma wa sọ on.

# AWỌN ỌMỌ ẸGBẸ UPGA MẸTALA TI WỌLE

**ẸNUGUN: Gbogbo enia lo nfosoke ti nwọn si ho iho ayọ ni kutukutu owurọ ana ọjọ Aiku tiiṣe ogunjọ oṣu yi nigbati nwọn gbo lati ẹnu ẹro asoromagbese pe, awon omo ẹgbẹ UPGA mẹtala lo ti woie ni Ipinlẹ Ila Orun nisisiyi laiko ni alatako kankan.**

Onirohin wa ni ilu Ẹnugun fi ye wa wipe ti ilẹ ana fi ṣu ni awọn enia na fi njo ti nwọn si nyọ ṣẹṣẹ.

A gbọ wipe lati owurọ na ni awọn alejo ti nrọgirigiri ninu ile awọn enia na, ti nwọn si nja nkan s'ara titi di alẹ ana.

Irohin na tun sọ siwaju pe, ọmọ ẹgbẹ Alakukọ ni gbogbo awọn mẹtala ti nwọn wọle na patapata.

Orukọ awọn enia na ni wọnyi.

Dokita B. U. Nxeribe (Iwọ Orun Oru) Ọgbẹni Nelson Olugu (Ila Orun Nsukka) Ọgbẹni Dennis Ahamefule (Iha Gusu ati Iwọ Orun Okigwi) Ọgbẹni John Ode (agbegbe Obudu.)

Ọgbẹni Morris Nnorom (Ila Orun ati Ariwa Okigwi) Ọgbẹni James Obioah (Iha Ariwa Orlu) Ọgbẹni Francis Agbarakwe, (Iha Gusu ati Ila Orun Orlu) Ọgbẹni P. O. Igwe (agbegbe Ezza-Abakaliki

Ọgbẹni F. E. Offor ti o ti fi Igbakan jẹ akọwe Ile Igbimọ aṣofin labẹ Minista Alamojuto eto igbokegbodo ọkọ.

(Iha Arin Okigiri) ọgbẹni Nwagede Nwangbo agbegbe Ishielu) ọgbẹni Sylvesta Alumoh, (Agbegbe Arin Nsukka. Dokita K. O. Mbadiwe ati ọgbẹni Mbazulike Amechi.

Nisisiyi, aye ijoko mẹtadinlọgọta lo ku ti n w ọ n yio dibo yan awọn enia fun si Ile Igbimọ Aṣofin apapọ Ijọba nisisiyi ni Ipinlẹ Ila Orun Naijiria.

Bakanna, ẹwẹ ni enia mọkanla ti wọle ninu awọn



Dokita MBADIWE

ọmọ ẹgbẹ N. N. A. ni Ipinlẹ Ariwa.

Gẹgẹbi Irohin ti o tẹ wa lọwọ lana a gbọ wipe Alhaji Abubakar Tafawa Balewa Alakoso Apapọ Ijọba ti wọle laiko si alatako.

Orukọ awọn e n i a ti o wọle laiko si alatako niwọnyi Malam Muhammadu Sanni Abubakar, Malam Muhammadu N i n g i Alhaji Adama Sirikin Tafarariki, Alhaji Saidu, Malam Iro Mani,

Malam Sule Sarkin Sulubewa Alhaji I b r a h i n Iyan Katsina ati Malam Abdullahi Inde.

Bakanna ni Alhaji Waziri Ibrahim, ẹniti o ti jẹ Minista Alamojuto eto idagbasoke iṣẹ Aje ati A l h a j i Musa Yar'Adua, Minista Alamojuto eto igboro ilu Eko t i wọle laiko si alatako



Alhaji Abubakar

WO OJU EWE KẸFA

## Ha! Ẹni Rere Lọ Ni Israeli !!

EKO: Ariwo nla, okiki si kan kakiri gbogbo igboro ilu Eko titi de Oke-Okun nigbati Ọgbẹni S. Abayọmi Fujah, jalaisi ninu Ile rẹ ni nọmba 20, Ọkọya Street, Eko, ni alẹ ana ọjọ Aiku ti iṣe ogunjọ oṣu yi, lẹhin igbati o ti di ẹni arundinladọrin ọdun laiye (65 years).

Ologbe Abayọmi Fujah jẹ ọkan ninu awọn oṣiṣẹ Ọkọ Reluwe ti o ti gba isimi ifẹhinti lẹnu iṣẹ nigba aiye rẹ, gbogbo awọn ara ilu Eko ni nwọn bẹrẹsi ṣe idaro yika gbogbo ilu Eko lana pe, "HA! Ẹni rere lọ, oninure a ti olore enia ku !!"

Olegbe Fujah jẹ ọ k a n ninu awọn Ọjọgbọn ti o ni imọ ijinlẹ ninu ẹkọ o si ṣe iwe kan nipa iṣiro o w o lede Yoruba, eyiti gbogbo aiye, paapa a w ọ n ọmọ Yoruba nra lọja bi akara gbigbona.

Ọmọ marun ni Ọgbẹni Fujah fi silẹ ki o to jade laiye ninu wọn ni Omidan Fọlọrunshọ Fujah, Dupẹ Fujah, ẹniti o wa ni Londọn nisisiyi fun itẹsiwaju ẹkọ; Awo Fujah on na wa ni Londọnu Kẹhinde Fujah ati Ladipọ Fujah.

Nwọn yio ṣe aisun oku na ni alẹ ọla ni nọmba 20, Ọkọya, nwọn o si ṣe e t o isikurẹ ni deede a g o g o mẹrin irọlẹ ọtunla ni itẹ oku Ikoyi, nibiti nwọn o gbe ṣe isin ikẹhin fun un.

Ki Ọlọrun da awọn ọmọ rẹ si o. Amin.

## KERESIMESI ỌDUN DE !

Njẹ o ha ti ri owo ti o fẹ fi ṣe ọdun ti mbọ yi bi? Bi bẹ kọ, kini ha se ti o ko fi yara tete lọwọ ninu idije ẹbun orire pọnun marun (£5) ninu Iwe Irohin Imọlẹ.

Owo yi le jẹ tirẹ bi o ba lọwọ ninu idije na ti o si gba pọnun marun (£5) na lọfẹ.

Wo oju ewe iwe kẹta ki o si kọ itan tirẹ ranṣẹ si olotu loni. Maṣe ju ẹbun nla yi nu. Owo Ọdun ni fun awọn ti nkọ Iwe Irohin Imọlẹ.

# IWE SI OLOTU

## Ẹ Jẹ Ki A Ranti Olore Wa.

Olotu, Jọwọ gba mi ni aye diẹ ninu iwe nyio oloyinmọmọ lati kesi gbogbo awọn ọmọ ilẹ Yoruba lati oke del'ẹ lati le ranti olore wa eyi ti işe olori ẹgbẹ Afẹnifẹre Oloye Ọbafemi Awolọwọ lori nkçan ti o şe si ilẹ Yoruba lọjọ oni eyi ti a ko gbọdọ gbagbe lailai

Nitori eyi ohun to jẹ pe a le fi san ẹsan ore ti o şe fun wa ni pe ki a dibo fun ẹgbẹ Alakukọ ati Afẹnifẹre lati le jẹki Oloye wa Ọlọla wa ati Baba wa Awolọwọ le jade lọgba ẹwọn.

Nitori eyi ẹnyin ọmọ Yoruba ẹ jẹ ki a kọ owo awọn onikumọ ẹgbẹ Dẹmọnu silẹ lati le da Oloye Awolọwo lare ati lati le san ore ti o şe silẹ Yoruba fun. Olotu modupẹ fun aye ti ẹ gba mi.

Emi ni,
P.O. Oshinukan
IJẸBU-ODE

## Anfẹ Irohin Imolẹ Ni Oyo

Olotu Jọwọ ma salai şe iranlọwọ yi fun awa ọmọ ilu Ọyọ lọna to jẹ pe a o fi ma ri iwe nyin Irohin Imọlẹ ka lojojumọ ni ilu Ọyọ gẹgẹbi nwọn ti şe nri ka ni awọn ilu miran patapa julọ o jẹ ohun to mu ilọsiwaju ba awọn mọ ile ẹkọ nitori pe ọpọlọpọ ọgbọn ni a nri kọ ninu rẹ ati pe a tun nri itan ka ninu sẹ.

Olotu Inu mi yio dun bi ẹ ba le şe iranlọwọ fun wa lati le jẹ ki a ma ri iwe nyin na ka ni ilu Ọyọ eyi to jẹ pe iwe na gan na ni yio jẹ iwe Irohin lede Yoruba ti yio ma jade ni ojojumọ irin wa yio dun bi ẹ ba le tete şe iranlọwọ eyi fun wa lati le jẹ ki a ma ri ka nigbagbogbo. A si nre ti nyin bayi o.

Emi ni Disu Alabi
ỌYỌ.

## Adegbenro E ku Asẹhin de Mama

Olotu jọwọ gba mi ni aye ninu iwe nyin Oloyinmọmọ lati ki Adele Olori ẹgbẹ wa Alhaji Danda Soiroye Adegbenro lori mama rẹ ti o jalasi ni ọjọ ku ti se ọjọ kẹtadinlogun osu yi ni ilu Abẹokuta mọ si ba Alhaji Adegbenro yọ pe o gbehin iya rẹ eyi ti gbogbo enia ntọrọ adura pe ki Oluwa le jẹ ki ẹn rere kẹhin wa,



Alhaji D. S. Adegbenro

Mo si ki Alhaji Adegbenro ku inawo ati pe ọmọ rere wa yio ikẹhin on Mama oniru rere to jaaisi na yio si tun gbe leke awọn ọta rẹ lagbara Oluwa. Awa ọmọ ilẹ Ijẹbu si mọ pe ko si ohun ti yio se ti koni fi di Olotu Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun nitori pe tirẹ ni Isẹ Olotu mo dupẹ o ọkọ Ọba ko ni sa nyin lẹsẹ Amin.

Emi ni
Adeşina Dauda
IJEBU

## Alaye Lori ọro Ọlawoyin

Olotu inu mi yi yio dun bi ẹ ba le gba mi ni aye die lati ba awọn ọmọ ilẹ Igbomina sọrọ lori alaye ti ọgbeni J. S. Ọlawoyin şe pe ti ẹgbẹ UPGA ba ti wọle ibo yi pe gbogbo ohun to udun ọmọ ile Igbomina ni awọn yio şe.

Şugbọn ohun to dẹ mu ileri na şe ni pe ki awa ọmọ ilẹ Igbomina dibo fun Ọgbẹni Ọlawọyin ki a si lọ si ile lasiko idibo ati pe ki a kọ ẹgbẹ Olmi silẹ nitori a ko ri nkan ti ẹgbẹ na şe fun wa lati ọdun mẹwa ti nwọn ti nşe akoso Ijọba apaqọ.

Ọgbẹni wa Ọlawọyin lo le mu ki ilẹ Igbomina ni irọrun ati alafia ti a ba le dibo wa fun. Ẹnyin ọmọ ilẹ Igbomina ẹ jẹ ki a dupẹ lọwọ Ọgbẹni Bay ọ Tiamiyu ati Ọgbẹni J. K, Balogun lori akitiyan awọn isẹngbe Ọgbẹni Balogun ni ilu kọọkan. Oluwa ko jẹ ki ẹ şe wa hala lasan a si mu oke lagbara

Emi ni
J. A O. Eniomikukute
Igbomina.

## E maa Ka Iwe Irohin Imọlẹ Lojojumọ

GBOGBO ARA ILU NKỌ ORIN IYIN AYỌ NIPA "DYNAMIREN" TỌNIC

ALE-BI-ALE Egbogi Tọniki Jamanu titun ti gbogbo ara ilu Eko ati Jakejado Naijiria mọ daju fun Akọ agbara ati Ajẹbidan işẹ rẹ lara Agbalagba Ọkunrin gbogbo.

Bi arẹ ara ba nmu ọ, nigbakugba fun wahala lala şişe ti o ko le jẹun daradara, tabi ki o male sun dada ọkun lọsan tabi awọn işan ara rẹ gbogbo ko ba şişẹ daradara ti Eemi Breath) inu rẹ ko ba gunlẹ daradara fun işẹ tabi wahala şişe tabi fun awọn ailera gbogbo' tabi ti ọjọ ori rẹ (age) ba ti kọja ọgbọn ọdun o si de adọrin tabi jubẹ lọ. Mọ daju pe "DYNAMIREN ni egbogi ti o nfẹ lati sọ'ara rẹ di ọtun pa tapata ara rẹ a si jọlọ, ẹran ara rẹ ti o ti hunjọ yio yi po pada patapata alafia ati gbadun yio de si ọ Iyẹn bẹ.

Bere egbogi na ni Şọbu



NIGERIAN MEDICENE STORES
4, Tinubu Square Lagos

ADEDUN CHEMIST
14 Wakeman Street Yaba

## IDIJE ! IDIJE !

A fi eyi kede fun awọn Onkawe Irohin Imọlẹ at a wọn Ọmọ karọ-o-jire pe a nfẹ

## ITN L'EDE YORUB

Eyiti ẹnikẹni ko ti tẹ jade ninu iwe ri tabi ti nwọn ko ti sọ lori ẹrọ Redio ri Ẹnikẹni ti o ba le lori yio gba

**(£5)** PỌNUN MARUN

Akiyesi;- Kọ itan tirẹ ki o han rekete, ti ẹniti ko bi han a o fa ya ni, ki o si mọ dajudaju pe ko ni ipa ninu Idije na, ITAN ẹniti o ba si daraju a o tẹ ade ninu Iwe Irohin Imọlẹ yi a o si fi lọ(£5 Posta Order) ranşẹ si

Fi Stamp Tọrọ (3d) ranşẹ fun gbigbe Pọnun marun (£5) ti o ba jẹ pada si ọ. Ki o ge ibiti Idije yi wa, ki o si fi ranşẹ pẹlu Stamp tọrọ rẹ si wa. Ẹnikẹni ti ko ba ge Idije tirẹ ranşẹ siwa ti o ba jẹ iwo na a ko ni fi ranşẹ si.

Orukọ............................................

Ibugbe............................................

............................................

Fi itan rẹ ranşẹ si:-

**Olotu Irohin Imọlẹ**

16, BAMGBOSE STREET, LAGOS.

# Idi Pataki Ti O Fi Yẹ Ki A Kọ Ẹgbẹ Olomi Silẹ Ni Ilẹ Igbomina

Lati Ọwọ J S ỌLAWỌYIN

Nitori pe:- Ẹgbẹ Olomi ko fẹ ire ati Ilọsiwaju ilẹ Igbomina Melo ninu awọn ọmọwe ilẹ Igbomina ni awọn Olomi ilẹ Igbomina wa ipo giga fun ni Ilọrin, Kaduna, ati Eko?.



Alhaji Ahmadu Bello
Olori Ẹgbẹ Olomi

Awọn Ọba ti nlọsi Council ni Ilọrin kosi Ọba ilẹ Igbomina kankan nibẹ abi awọn ọmọ ẹgbẹ Olomi ko si ninu ẹgbẹ ni lasiko ti wọn yan awọn Ọba wọnyi ni?.

Ẹgbẹ Olomi ilẹ Igbomina lo ṣa gbogbo ọmọ Igbomina ti Ọlọrun fun ni aisi ki owo jọ, ninu Ọdun 1962 Ti nwọn pe wọn ni (Minister ati Honourable) olowo wọn gba owo bi Ẹgbẹrunmẹfa £6, 000 lọwọ wọn ti wọn si ṣe ileri Ominira ilẹ Igbomina, lẹyin oṣu keji ti wọn gba owo. Gbogbo owo yi ni ẹgbẹ Olomi ıl Igbomina ti na o si a Ominira titi di oni lti Ọdun 1962.

Eyi ti oburuju ni wipe, ẹnitiṣafi ṣe asiwaju f n omi nira ilẹ Igbomina yi Miuister Olomi ilẹ Igbomina sọ wipe awa ko gbọdọ sọ ọrọ Divison sinu iwe Irohin, tabi Radio mọ awa kosi ipade nipa rẹ mọ.

Ẹgbẹ Olomi ilẹ Igbomina nọ jẹ ẹgbẹ ti mada ija silẹ larin ilu kan si ekeji fun apẹrẹ ija ọja oro ati okeọla Eyi ti ilu mejeji na owo toju £19, 000 lọsi ija Omupo ati koko ija oye Baalẹ Ọjọmu.

Awọn ẹgbẹ Olomi logbẹ Kọla ni akowe si Ajaṣẹpo Ti o jẹ wipe ojojumọ ni Kọla Apado yi fi nbu Ọba wa Olupo ti ilu Ajaṣẹpo Ti ara kunrin yi si nṣe ni Ọba ni Ajaṣẹpo Ẹnikẹe ti o ba ri wipe, ko ṣe ẹyi oslomi agba iru ẹnibẹ ai na Oluwarẹ.

Awọn ẹgbẹ olomi yi n on lo awọn alikali ni Ilo kulo, lati mada iyajẹ ọmọ ẹgbẹ Ọlọpẹ ati iti maju wọn si ẹwọn lainidi

Awọn ọmọ ilẹ Igbomina kiṣe ẹniti ori rẹ kope dibo ki wọn tun dibo fun olomi iru janduku wọn si Ọba, Ijoye sanmori ilu ati ara ilu

Ẹgbẹ Olomi lo da Council Ijọba ilu Igbaja d u r (Districts) Head Counc of Igbomina

Melo ni ilewe ti awọn ẹgbẹ Olomi Igbomina ṣe agbara lati ọwọ Ijọba olo?_ mi wọn si ilẹ Igbomina Melo ni ile Iwosan (Hospital) ti Ijọba Olomi ṣe sii Igbomina.

Awọn enia ilẹ Igbomina ti awọn ẹgbẹ Olomi ilẹ Igbomina ju si ẹwọn ko ṣe l'onka laiṣẹ, lairo

Ẹgbẹ Olomi ni ko jẹ ki wọn si Post Office Ajaṣẹ eyi ti Iju Ajaṣe kọ fun ara wọn

Ẹdibo fun J S ỌLAWỌYIN ki Ominira lebade ilẹ Igbomina ti a o si g ba (Divison) lai da owo kan kan ki a si bọ ni oko ẹru



Ogbẹni J. S. Olawọyin
Olori Ẹgbẹ Afẹnifẹre Ni Ipinlẹ Ariwa

## YE IRAWỌ RẸ WO

AQUARIUS (Jan 22 – Feb 20) Mase fi ika ju se ohun kan loni ki oma ba gbagbe isẹ pataki kan lati se mase gbẹkẹle ọrẹ ki wọn ma ba basẹ rẹ jẹ, sọra rẹ.

PISCES (Feb 21 - Mar 20) Mase fi ara silẹ fun a r ẹ ki osi ja fun ẹmi ara rẹ, sọra lọdọ awọn ọrẹ titun ti o n i ba obinrin ti o nfi oju pe ọ sere papọ kọ si ewu

ARIES (Mar 21 - April 20) Nkan ko ni lc daradara ni owurọ, yio si suwọn ni ọsan, bi ba fẹ kọwe si enia sọra ki ma ba di ọrọ kotu.

TAURUS (April 21 – May 20) Ayipada diẹ le wa nipa igbesi aiye ara rẹ, mase daba lati yi pada, nse ni ki o gba a kadara.

GEMINI (May 21 - June 21) Sọra rẹ, ki olọ sakiyesi gẹgẹbi oti nnawo, nitoripe owo pupọ ni onwa l a t i fi gbe isẹ duro.

CENCER (June 22 - July 22) Mase sisẹ ni yọbọkẹ loni nitori gbogbo ohun ti o ngba ni ero ni yio di otitọ

LEO (July 23 – Aug 23) Isẹ ode gbangba lo dara fun ọ lati se loni, tabi isẹ ẹgbẹ, orisirisi ni iwọ yio se l ọ j ọ Monday

VIRGO (Aug 24 – Sept 23) Sisẹ taratara ki osi ninu orun, li oba sisẹ ni yọbọkẹ ẹnu yio ya ọ lati ṣe bẹ.

LIBRA (Sept 24 - Oct 23) Ibiti mejeji ti iwọ yio l ọ oni yio se, ọ ni anfani rẹpẹtẹ.

SCORPIO (Oct 24 – Nov 22 Iwọ yio ba ẹgbẹ lọ s i ode faji loni ode ti iwọ yio lọ ni asalẹ yio mu isora dani sugbọn iwọ yio ri nkan ayọ se ni ọjọrọ.

SAGITTARIUS (Non 23 - Dec 21) Tẹle i m ọ r a n ọkan rẹ ki osi se ohun kan tl o ti wa ni ọkan rẹ lati s e iwọ yio gbọ irohin ẹni atijọ kan.

CAPRICORN (Dec 22 - Jan 21) Iwọ ti nreti lati r Iwe akan gba lati ọdọ awọn enia rẹ, mase saniyan lori alawe ọnko si ohun kan lara wọn.

E Ma a Polowo Ọja Nyin Sinu Iwe Irohin Imọlẹ Lojojumọ

# Abanijẹ Ẹ ku Ọfọ

## Lati Ọwo Ahadji Y. A. Disu

Ọlọrun Ọba awọnano ṣe ẹda gbogbo awa ọmọ enia. On ni o da iwọ On kanna sini ose ẹda emi na. Idi pataki ti o si fi ṣe ẹda wa ni pe, ki a ma a jọsin Fun un ni ọna ti o fi lelẹ fun gbogbo wa yika igun mẹrẹrin aiye.

Ni ọna ti o tọ ti o si yẹ Mimọ ni Ọlọrun. Ọna mimọ si ni o fi lelẹ lati ma a sin in. Idi keji ni pe, ki a fẹran ara w daadea Ki a si ni ifẹ ọmọ enia ti a ti mọ ri ati eyi ti a ṣẹṣẹ mọ, gẹgẹbi a ti ṣe fẹ ara wa ati awọn ọmọ wa. Eyi ni akoja ofin Ọ l ọ r u n Olodumare Ẹnikẹni l'ọkunrin ati l'obinrin ti o ba si gbinyanju mu ofin na lọ, gbogbo ohun ti o ba si da ọwọ rẹ le, yio si yọri si ire pẹlu irọrun.

Gbogbo ọmọ enia ni



Alhaji Y A Disu

Ọlọrun ṣe ọla fun. Ko ṣe wa ni alaini lakaye gẹgẹbi ẹ r a n k o. K o si ṣe ẹda wa ni alaabọ lakaye o da wa pe perepere. O ṣe ẹda wa lati mọ ohun ti ko dara.

Ṣugbọn o ṣe ni ni engmọ lati ri pe, o mbẹ ninu awa ọmọ enia ti o ni oju ti ko si fi riran, ti o ni eti ko si ft gbọran ti ko si wo oyce rara,. Gbogbo ero irui; awọn enia bẹẹ ni pe ki nwọn ma a ṣe iṣẹ okunkun ki nwọn ma a ṣe iṣẹ ibi. Nwọn ki i fẹ lati ri ẹni ti o ni ilọsiwaju ninu ẹbi wọn tabi aladugbo wọn tabi larin ilu ti nwọn bi wọn si, nwọn a ti ma a ba a jẹ, kakiri nitoripe eṣu ti jẹ wọn lere. Eṣu si ti sọ wọn di ABANIJẸ-ALAROKA.

Nwọn ko lẹ ronu jinlẹ lati mọ pe, Ọba ẹlẹsan ni Ọlọrun, olukuluku wa ni yio si jere iṣẹ rẹ. A ki i si gbin alubọsa ki o hu ẹfọ melo melo ni ojo ti rọ ti ılẹ ti fi mu. Melo - melo ni awọn ABANIJẸ ti awọn ti ke igbe oro ku, Ẹẹsan kogbọ oogun. Ẹ l ọ ronu jinlẹ ki ẹ si yi iwa pada. Ẹ ye da adapa irọ mọ ọmọ enia mọ. Abanijẹ kii gba iyi, Abanijẹ ẹ ku Ọfọ Ọlọrun ju nyin lọ. Mo ṣe iranti itan baba dudu doogo alaṣọ d u d u Abanijẹ Kẹnimani kan ti o ni ẹ t ọ ju ẹnikẹni lọ lati jẹ oye lemọmu si Mọṣalaṣi olokiki kan. awọn jaamọ Mọṣalasi kọ ọ silẹ. Nwọn ko fii jeẹ, nitori iwa aimọ a ni i w a aiṣododo rẹ ati iwa abanijẹ ati iwa kẹnimani ti o nhu.

Mo si ṣe iranti Ọgbẹni kan ti apele orukọ rẹ n j ẹ DURO-DEEDE. Nṣe ni o nri igbega ni ibiṣẹ ti o si ngba iyi kaakiri nipa iwa ire rẹ ati iwa ifẹ ti o n h u si t'aja t'ẹran ati si awọn ọmọ iṣẹ rẹ. Orukọ DURO DEEDE na ni 'Niyi: COK.

a jiroro, oruko awọn ore rẹ na ni si AJAKO, AYẸ, AKATA OGO WẸẸRẸ, KỌLỌKỌLỌ ATI ẸYA, ti gbogbo wọn jẹ odẹ apẹran jẹ ati Mujẹmujẹ

Ninu ipade kan ti awon Tẹmbẹlẹ yi ṣe, Ikoko kọ won wipe, ki awon parapọ o so fun Erin wipe, ki o lọ ranṣe si Kiniun wipe, ki o fa RỌRỌ ỌRUN rẹ larin ọjọ meje, Bi ko ba le fa RỌRỌ ỌRUN re larin ọjọ meje, gbogbo awọn ọmọ ẹ r a n k o yio p a r a p ọ

IYOKU DI ỌLA.



EGBOGI AWỌN ARA ILU FARANSE

**TESSYDRE**

Fun Ọmọ — Ọwọ Ati Ọmọde Gbogbo

Tessydre jẹ ojulowo egbogi haunhaun ti meji irufẹ bẹ kosi kakiri igboro ilu Nigeria fun itọju ọmọ ọwọ tabi ọmọde lati le jẹ ki wọn ma hu EHIN ẹnu wọn pẹlu irọrun laisi wahala rara tabi aikole sun yala lọsan twe sun awọn iya wọn gbogbo Ogọrun orisirisi egbogi bayi ni wọn npolowo sinu ẹrọ gbohungbohun ati sinu iwe kika lojojumọ ṣugbọn kosi eyi ta le fi we egbogi Tessd re rara o. Ọlọgbọn di ori ẹja mu pupọ ninu awọn ara ilu Saro ati awọn ara ilu Agonyin (CHANA) mọ egbogi yi dajudaju on na ni wọn si nlọ fun awọn ọmọ ti wọn ba ṣẹṣẹ bi titi fi di nkọn bi ọmẹ ọdun wawa gbako. Kosi wahala tabi iyọnu inu rirun ọka ori inu iwọ aiperi osiin u fẹkun fẹkun ewo, kokoro ara lapalapa ara gbigbona igbẹ ṣiṣu, gburu tabi aikolokun ninu ara sisu, Inu kunkun iro afẹfẹfẹ ati orişirişi awọn amodi tabi aisan ti o ma nyọ awọn ọmọ ọwọ lẹnu nigba Ehin HIHU" gbogbo. Tessydre a ma a mu ki ehin ẹnu rẹ ọmọ rẹ lagbara gidigidi at san ara wọn pẹlu.

Awọn ọmọ ti wọn nlo egbogi yi ki saba ṣe ama rara niwọn igba ti wọn ba ti ngbọṣẹ dede, ti otutu ko si le ri aye lati duro ni igbaya wọn ti wọn jẹun dara dara ti nwọn si nsun gbadun pẹlu

Bere Egbogi Ni Ṣọbu Awọn:—

WATERLOO STORES

8, Palm Church Street, Lagos

ADEDUN CHEMIST

4, Wakeman Street, Yaba

## Lati Oju Ewe Kaji

Olu Igbo ati olori Onidajo gbo gbo awọn ẹranko Iwọ ni o si lagbara ju gbogbo ẹranko ti o mbẹ ninu Igbo lọ, jọwọ ṣe ati lẹhin fun mi ki njoba ropo Kiniun nitoripe Ika ni Kiniun, ojojumo ni o npa awon omo ẹranko jẹ

Lati ojo yi ni Erin ti nwa ona ti yio fi gbe otẹ dide si Kiniun ki o si paṣẹ fun gbogbo awon ẹranko p e k i n w o n le kiniu kuro lori itẹ rẹ Nigbati Erin ko tete kọbiara si mutumutẹ wọnyi ni Ikoriko ba lọ wa awon ẹlẹgbẹ rẹ kan kun ra, lati maa ba

# IROHIN IMỌLE

*IMỌLE ORE AIYE, TLNI GBOGBO LAWA*

NO 877 MONDAY DECEMBER 21, 1964 (2D)


## Ọkunrin Kan Lu Iyawo Rẹ Pa !

ABAKALIKI:— Idaamu nla ba gbogbo awọn enia ti nwọn wa ni tosi nigbati Ọkunrin kan ati iyawo rẹ Iyaafin Nkwegu Nwambo, ẹni ọdun mejilelọgbon bẹrẹsi ja ija ajakuakata ti Ọkunrin na si sare wọle ti o muada jade ti o si ṣa iyawo rẹ pa ni opin ọsẹ to kọja yi-

Irohin awọn Ọlọpa Ẹnugun fi ye wa wipe nigbati ija na bẹrẹ gbogbo awọn ara ile lo kesi tọtun tosi ti awọn mejeji ko si gbọ ni nwọn ba sare wa pe awọn Ọlọpa ni Tesan, Ṣugbọn nigbati awọn Ọlọpa yio fi de Ọkunrin na ti lu iyawo rẹ pa bamubamu nwọn si ba Iyawo na ninu agbara ẹjẹ gbigbona.

Ọkan ninu awọn ọ l ọ p a na ṣe alaye fun oniwe Irohin wa ni Ẹnugun wipe awọn lero wipe ọkunrin na ri iyawo rẹ pẹlu ọkunrin miran nibiti nwọn gbe nba ara wọn tayo, ki onitọhun to salọ.

Lẹsẹkẹsẹ ni ọkọ obinrin na ti sakuro nile nigbati o lu i y a w o rẹ pa tan awọn ọ l ọ p a ti gbe oku Iyawo rẹ lọ si Ile iwosan lakulaku, nwọn si nwa ọkọ obinrin na lọwọ bayi.

Bi awọn ọlọpa ba ti ri ọkunrin na ẹ o tun ma gbọ ninu iwe irohin wa.

# AWỌN OṢIṢẸ BINU DA IṢẸ SILẸ

MUSHIN

**Ọgbẹni E. J. Fry Ọga agba Ile iṣẹ "Messrs Vono (West Africa) Limited" Mushin, ti kọ iwe si gbogbo awọn oṣiṣẹ ile iṣẹ wọn bi Ọrindin ni Irinwu (320) ti nwọn ti binu da iṣẹ wọn silẹ lati ukan bi ọjọ mẹwa sẹhin pe ki gbogbo wọn yara tete pada si ẹnu iṣẹ wọn kiakia.**



Ọgbẹni IMODU

Ninu ọsẹ keji sẹhin ni gbogbo awọn oṣiṣẹ na binu da iṣẹ sllẹ. Ohunti awọn oṣiṣẹ na nsọ ti wọn fi da iṣẹ silẹ ni wipe awọn nfẹ owo ẹbun lati fi ṣe ọdun Keresimesi ti mbọ yi.

Ọkan ninu awọn oṣiṣẹ na ṣe alaye fun oniwe Irohin wa ti o lọ wo ninu ọsẹ to kọja yi pe, awọn ko ni pada si ẹnu iṣẹ awọn a fi bi awọn ba ri ẹbun owo ti awọn yio fi ṣe Keresimesi gba.

Ọgbẹni Fry, ti iṣe Ọga agba ile iṣẹ na ṣe alaye fun Oniwe Irohin wa Ejongbo ro ni Ijẹta wipe, nigbati awọn Oṣiṣẹ na ri iwe on gba were, ni awọn mẹtadin logun ninu wọn ti sare wa bẹrẹ iṣẹ wọn.

Otun ṣe alaye pẹlu wipe, Ile iṣe on ko ni san owo oṣu gbogbo asiko ti awọn Oṣiṣẹ na ko fi wa si ibi iṣẹ fun wọn.

O ni, nigbati oṣu ba pari awọn yio yọ owo iye asiko ti awọn Oṣiṣẹ na ko fi ṣiṣẹ Iye ọjọ ti nwọn ba ṣiṣẹ ni nwọn o gba owo rẹ.

O tun ṣe alaye siwaju si awipe awọn Oṣiṣẹ na ti ba adehun ti nwọn ba ile iṣe ou ṣe ki nwọn to wọ iṣẹ nipa iṣẹ ti nwọn binu da silẹ.

Ọgbẹni Fry wa ṣe afikun ninu ọrọ lẹ wipe bi awọn enia na ko ba fi pada si ẹnu iṣẹ wọn ni awurọ yi ọjọ Aje ti iṣe ọjọ kọkanlelogun oṣu yi gbogbo wọn ni awọn yio da duro ti awọu o si gba awọn enia miran dipo wọn

Bi awọn oṣiṣẹ na ti ri iwe yi gba ni awọn mẹtadinlgun ti yara lọ bẹrẹ iṣẹ wọn ni ọjọ Bọ ti iṣe ọjọ kẹtadnlogun oṣu yi.

Asi lero wipe gbogbo awọn Oṣiṣẹ iyoku ni nwọn yio pada si ẹnu iṣẹ wọn ni owurọ yi.

Ṣugbọn bi awọn enia na ko ba pada a lero pe, gbogbo wọn le padanu aye iṣẹ wọn lẹnu iṣẹ na.

Oniwe Irohin wa, Ejongboro yio lọ si Ile iṣẹ na ni owurọ yi, yio si sọ fun nyin Ohun yowu ti o ba ṣẹlẹ ninn Ile iṣẹ na ni owurọ ọla.

## Lati Oju Ewe Kini

Irohin fi ye wa wipe Ọlọla Frances Ibiam, gomina Ipinlẹ Ila Orun Naijiria ti kọwe si Ọlọla Azikiwe nipa iwe ti gomina na ri gba nigbagbogbo wipe, okeṣoro kan wa fun awọn ni apakan orilẹ ede yi lati fi orukọ awọn aṣoju awọn orilẹ fun ibo didi.

Iwe na tun sọ siwaju pe, nwọn ko ri awọn akọwe alamojuto eto ibo ni Ile iṣẹ wọn lati gba iwe iforukọ silẹ lọwọ wọn.

Bakanna ẹwẹ ni awọn ọlọpa ngmu awọn Asoju miran kakiri awọn agbegbe kan eyi si mu ibẹru wa ti awọn Asoju fi nlọ sapamọ ki ọlọpa o bi mu wọn."

Pelu ẹbẹ on itẹriba ni mo fi kọwe yi si nyin lati le ri wipe ki ẹ lo aye nyin ki ibo ti nwọn fẹ di yi le jẹ eyiti gbogbo enia o di lọna ẹtọ ati laikosi ifoiya ki orukọ rere orilẹ ede yi le ba niyi loju gbogbo enia nile ati ni Oke-Okun, ati ylka gbogbo aiye.

A tun gbọ l.bẹlẹ wipe, awọn kan ti tun wọle laiko si alatako, bi a ba ti g b ọ Orukọ wọn si, ẹo tun ma ma gbọ ninu Iwe Irohin wa.


## IPABE UPGA

Awọn ọmọ ẹgbẹ UPGA yio ṣe ipade loni ni deede agogo marun irọlẹ ni opopo Ọbadina.

Awọn ti o wa ni Ebute Mẹtta yio ṣe ipade ti wọn ni Ọja Sabo, Yaba ni agogo marun kanna.

Nwọn npe gbogbo ọmọ ẹgbẹ lọkunr ati l'obinrin.

Tete ra Irohin Imọlẹ tirẹ lọla ki o ba le mọ ibiti wọn ma ti ṣe ipade ti ọla.


## IKEDE PATAKI

Njẹ o mọ awọn Aṣoju ti o fẹ dibo fun ninu ibo apapọ ti mbọ yi bi ? Bi o ko ba mọ wọn, kiniṣe ti o ko ma a ka iwe irohin Imọlẹ deede

Bakanna ni o mọ gbogbo bi nkan ti nlọ si ni orilẹ ede yi bi o ba nka Iwe Irohin Imọlẹ deede

Ka Iwe Irohin Imọlẹ Ọla lati mọ gbogbo awọn ọmọ ẹgbẹ Afẹnifẹre ti wọn fẹ dibo fun ninu ibo ti mbọ yi,


## ADURA JẸ J'OGUN LỌ

| | |
|---|---|
| Iwe Adura pataki fun Arisiki lati ilẹ Mesira | 2/6 |
| Iwe Adura Akanşe ati apẹrẹ ile aiye........................ | 2/ |
| Afọmọ - isin Ojiṣẹnla Muhammed........ — ...... — — | 1/ |
| Iwe Itumọ al ati Adura Ala Ibanujẹ........................ | 3/6 |
| Iwe Aniyan Irun ojojumọ ati Aniyan pataki fun Musulumi | 1/ |

Tete fi Owo ranṣẹ si:-

ẸSAN KOGBOGUN SERVICE
8, Idumagbo Avenue, Lagos Naijiria
(Leti Ọja Jankara l'Eko)



Printed And Published by Modupẹ Printing Press, 16. Bamgboṣe Street Lagos Phone 21985
Editor: TUNJI ADEOSUN 45, Campbell Street Lagos (20/12/64)